WANTED

Two An Advanced Apprentice Printers.

Apply in person to:-

Twin Printing Press
32, Tokunboh Street,
LAGOS.

IROHIN IMỌLẸ

MOTTO: IMỌLẸ DE, OKUNKUN PARADA.

READY FOR SALE

Iwe Arofọ ti -:
ANỌYIN LOHUN-BI-ỌMỌGE IMARO
APA KẸTA
LATI ỌWỌ
G. A. SOWUNMI
Price 2/-
Modupe Press
16, Bamgbose Street,
Postag Extra

VOL. I No. 45, WEDNESDAY MAY 7, — MAY 13, 1958 KỌBỌ KAN

# Won Bi 'OMO AGUNTAN' Pelu Iru Ati Eyin Kan Lenu

Ni ojo isegun ti o koja yi ni obirin kan ni Ogbomoso ni abule Elesi ti oruko re nje Sarah Aina bi omo aguntan kan ni Soosi Christ Apostolic Mission Akata lehin osu merinlelogoji ti o ti ni oyun.

Obinrin na sọ wipe oun ti wa ninu oyun fun oṣu mẹrinlelogoji ( 44 months )

Aladura Abraham Akintọla ti alasa ni ilu Ogbomọṣọ, ẹniti o gba obinrin na sinu ijọ sọ fun alagbọrọtẹ wipe ninu adura oun, Ọlọrun sọ fun oun wipe Sarah yio bi ẹranko, ẹranko na yio si ku. Ni ọjọ kọkandinlogbon oṣu April ni Sarah ti nje irora bi ọmọ ti nwọn ti nreti.

Ara ọmọ ti a bi ni oku yi kun fun irun ati wipe ajeji ọmọ na ni iru ati chin kan. Sarah sọfun alagbọrọtẹ ninu ọrọ ti a ba sọ lẹhin ti o bi ọmọ tan pe oyun oun gba ọdun mẹta ati oṣu mejọ. O sọ pe oun ti ni oyun fun igbamẹta, ti oyun na ba di oṣu kani o ma nbajẹ, mo ṣe ipinnu lati pe Kristi Apostolic Mission ni ori oyun igbẹhin lẹhin oṣu mẹrinlelogoji ti mo ti loyun, ohun ni o mu mi wa si Ogbomọṣọ, nigbati aladura yi sọ fun gẹgẹbi yio ti ṣe ri fun nigbati o wa ninu oyun, ko gba ọrọ na gbọ. Irun ọrọ na ti rọ, o si ti yipada si aṣọ funfun, eyi yi ni a fi we, ṣugbọn ẹyin na si wa nibẹ, ati wipe, laiṣeani ani, iru ọmọ ti a sọ yi ka wọlọwọlọ ni abẹ ọmọ ajeji na.

Aworan ọmọ na wa ni ọdọ aladura ni Ogbomọṣọ.

## AWON IWE KOSEMANI TI OWA NILE FUN TITA NISISIYI

| | |
|---|---|
| Afọṣẹ Iṣẹdalẹ Yoruba ati Psalm Ajẹbidan | 2/6d |
| Iwe Ẹgbogi Ajẹbidan pẹlu Itumọ Ala | 20/- |
| Itan Aladun Ede Yoruba | 3/- |
| Ajiran Ilu Oku | 3/- |
| Waka Bisiriyu Apalara | 1/- |
| Itumọ Ala ati Itumọ Ami Ara | 3/- |
| Iwe Owe Yoruba | 3/- |
| Psalm Iṣẹgun Ajẹ ati Aiye pẹlu Turari | 17/6d |
| Turari Itaja, Ẹyọnu Ajẹ ati Adura | 10/6d |

Fi owo ọja rẹ ati 1/- ranṣẹ si :-

Fi owo ati Stamp 1/- ranṣẹ fun gbigbe ọja rẹ pada
J.O. SHOYINKA c/o Post Office Ebute Mẹtta
Tabi
8, Ojo Road (Oduabọrẹ) Mushin,

AWỌN IWE TI A ṢẸṢẸ FẸ TẸ JADE

Igbo Eṣubeleke ( kikun ) 4/6d, Irin Ajo Ajanpako ( kikun ). 4/6d Ayunọrunbọ ati Panpalaṣọ 4/6d, Ajiran Ilu Oku ( kikun ) 4/6, Ṣebotimọ Ọrẹ mi 3/-, Mafarọ Ṣere 3/-, Igba ko lọ bi Orere 3/-

Akiyesi :- Ẹ o ma gbọ nigbati o ba jade

## OBA OBINRIN ATI OKO RE YIO BE ILU GHANA WO



LỌNDỌNU

Irohin kan wa wipe ọba obinrin ilu Geẹsi ati ọkọ rẹ yio lọ bẹ ilu Ghana wo ninu ọdun 1959. Dr. Nkrumah lo kọwe si ọba na ki o wa bẹ ilu Ghana wo.

Irin ajo kejila ni eyi yio jẹ fun ọba obinrin ilu oyinbo na ti o ba lọ bẹ ilu Ghana na wo lati igbati o ti gori oye ọba ni ọdun 1952, o si ti wa bẹ Naijiria papa wo ninu ọdun 1956.

Oba obinrin yi ran ẹgbọn rẹ kan ti o jẹ obinrin ti a npe ni Duchess of Kent wa si Ghana ninu oṣu March 1957, nigbati ilẹ Gold Coast gba ominira ti nwọn si yi orukọ ilẹ wọn pada si Ghana. Ọba obinrin yi ran ẹgbọn rẹ gẹgẹbi aṣoju Ọba fun isọdi ominira ilu na.

Ki Ade pẹ lori ọba wa, Ki bata pẹ lẹsẹ. Aṣẹ.

# IMỌLE

ẸSIN ỌRỌ WA:- IMỌLE DE OKUNKUN PARADA

*EDITORIAL WORKS & OFFICE*

**16, Bamgbose Street, Lagos**

**Telephone:- 21985**

*London Office:-*

*Sunday Ayorinde:- 5, Hemming Street London E. 1.*

UNITED KINGDOM REPRESENTATIVE

PUBLISHING DISTRIBUTING CO. LTD. MITRE HOUSE

177, Regent Street, London W. 1.

FUN OWO "IROHIN IMỌLE" ODUN KAN

**EKO**— Ṣile Mẹrin ati Kọbọ Merin (4/4d)

Ilu miran ni Naijiria ati Oke-Okun, Ṣile Mefa ati Kọbọ Mẹfa (6/6d)


# ERO ILU OYINBO E KU ABO O

ENIKẸN ti o ba bere yio ri gba, ẹniti o ba kankun ni ao si silẹ fun. Ohun pataki tia le sọ nipa awọn ọmọ ti Ijọba ko pada bọ lati ilu Oyinbo ni wipe nwọn nsa gbogo/agbara lati gb e ogo ilu Naijiria soke ṣugbọn rọ Ọlọru nkannalo sọ bayi pepupọ ni a pe ṣugbọn diẹ ni ao ri i.

Gbogbo wa lo mọ daju e pupọ ti ba oko siṣe lọ si ilu Oyinbo ṣugbọn nigbati o ya o joko s'ọhun o si kọ isẹ kan bọ pada wa si ile bẹ na si ni ọpọlọpọ ti j okọ ba lọ si ilu Oyinbo na ti o si pada wa di enia pataki lode oni ni ilẹ Naijiria.

Ṣugbọn nipa ti awọn ti Ijọba ko pada wọnyi a le ki wọn wipe nwọn ku igbiyanju nitoripe nwọn ko dabi ẹlomiran ti ko bikita rara, bakanna a le sọ fun nwọn wipe ki nwọn mase sọ IRETI wọn nu nitori ẹniti ko ti ku Ise rẹ ko tan, nigbati o jẹ wipe ẹ ko lọ fun ere ṣugbọn ẹ lọ fun ilọsiwaju Isẹ larin ilẹ awa enia dudu.

Nitorina a ki nyin ẹ ku abọ, ni otitọ ati ododo ẹ gbọdọ ṣiṣẹ karakara nitori ilu Naijiria ko gba gbẹrẹ mọ bi ti atẹhin wa.

Lakotan ara, ki eyi ma se ya yin lẹnu nigbati Ijọba ba nyọ yin lẹnu nigbati ẹ ba fẹ lọ si ilu Oyinbo fun ẹkọ, nitori ko ma ba si irufẹ irẹwẹsi bayi ni Ijọba se ma nsọ wipe ẹni latifi san iye owo kan silẹ.

Ọrọ Ọlọrun papa sọ bayi pe kise gbogbo awọn ti npe mi ni Oluwa Oluwa ni yio wọ Ijọba Ọrun" Kise gbogbo ẹniti o lọ si ilu Oyinbo nikan lo nilari laiye pupọ ninu awọn olowo wa ni ko lọ mu owo wa lati ilu Oyinbo, ṣugbọn lẹhi n ti Ọlọrun ti bo asiri ọpọlọpọ ni nwọn lọ fi oju kan ilu Oyinbo.

Pupọ Obinrin ode oni ni ko tilẹ fẹ lati fẹ ẹniti ko lọ si ilu Oyinbo, omiran ẹwẹ lẹhin ti o ba ta ti yio wa ọna lati lọ wa ọkọ lọhun. Eyi jẹ ohun ti ko dara rara ẹ jẹki ase ohunkohun ti a ba mase nihin ti o ba si wu Ọlọrun pe ki a de Ilu Oyinbo fun ilọsiwaju ẹkọ tabi nkan anfani miran, Ọlọrun na yio pese owo tabi ki Ijọba ran wa lọli ỌFẸ gẹgẹbi ọpọlọpọ ti mọ eyi. ẸNI TO SUBU KỌ ERO ẸHIN LỌGBỌN


DIRECT YOUR PRINTING JOBS TO:-

**MODUPE PRINTING PRESS**

16, Bamgboṣe Street, Phone 21985

LAGOS


# Iwe Si Olotu

## Oselu Ilaro, E wole, Kini o ku?

Mo ki awọn oṣelu ti o yege ibo ni Ilaro ku orire. Mo ba wọn yọ pupọ, Oluwa ko ni jẹki ẹnikan sina ninu wa. Ṣugbọn ati de ade ko ṣoro, ati lo ori oye si rere ni o ju.

O yẹ ki gbogbo oṣelu ma ranti nigbagbogbo pe awọn enia ni o ran awọn lọ sile iṣelu lati bojuto eto ilu ni orisirisi ọna; bi ilu ma tẹ siwaju, bi alafia yio se ma tẹ ni ilu, ati paapa julọ lati ma rii pe nina owo ori wa ko jẹ inakuna. O si yẹ ki awọn oṣelu ma ranti pe ti awọn ko ba lo aye wọn daradara si igbadun ati ilọsiwaju gbogbo wa ki iṣe awọn nikan ni yio jẹbi bikoṣe e bẹkẹgbẹ ti oṣelu ti nwọn ba wa.

Nitori eyi mo tọrọ aye lati tọka si awọn ohun diẹ ti o yẹ ki oṣelu Ilaro tete fi si ero wọn ni akoko yi, ekini ni wipe oju ọdun mẹta oyinbo lọ ti wọn ti bẹresi kọ ile itaja si ọja Ilaro ti o si jẹ pe nwọn ko yi ti kọ idamẹrin. kosi ẹniti ko mọ bi ile itaja daradara ti jẹ pataki to fun ilu. Aini ile itaja atata a ma jẹ ki ohun buruku bale ohun jijẹ lọja, arun buruku a si wọpọ ni ilu. Ẹbẹ wa nipe ki ẹnyin oṣelu jọwọ mura si iṣe ọja yi ki o le pari.

Ohun ekeji ti ngo mu ẹnu kan ni omi tita ni Ilaro. Iyanu nla ni o jẹ fun emi lati rii wipe awọn enia kan nilati ma fi omi Ijọba ti gbogbo wa ndawo si ṣe owo, iyanu ni o si tun jẹ pe awọn oṣelu joko, owọn kawo bọtan, kini anfani orogbo nigbana, ni igbati a pa ti ko lawẹ, ti a jẹ ti o nkoro? kini anfani oṣelu ti omi ni lara, kini anfani oṣelu ti o nri ohun buruku ti ko le tunṣe? ṣugbọn mo ni idaloju pe omi titun ti de, ẹja titun ti wọọ, ki ẹ fi ọwọ sọwọ ki ẹ mura.

Ko si anfani pe Ilaro ntẹsiwaju, nitori eyi o si yẹ ki a ma tẹsiwaju pẹlu rẹ. Nigbati a gburo pe nwọn yio tun gbọngan ile Orona kọ, inu gbogbo wa dun, ara wa ya, nigbati nwọn si pari rẹ, i n u wa tun dun si nitori ile yi ni orire pupọ, n iwọn igbati o ti jẹ pe ọpọlọpọ nkan bi ita iṣire ati ẹja ni wọn ti berẹ bi ọdun mẹta sehin ti ko yi si ti pari. A dupẹ pupọ fun ile Oronna na, ki Oluwa na tọ gbogbo nyin si ọna, ṣugbọn ita rẹ ko ba oju mu, ile Oronna dara ni iwọn, ṣugbọn ita rẹ ṣe abuku rẹ. O yẹ ki a tun ibẹ ṣe ki a gbin koriko oyinbo ati itanna si, ki a si mọ gbagede fẹrẹfẹ yi ka.

Mo mọ daju pe ẹo bere pe owo kọ ni ao fi ṣe? Ngo si dahun pe, bẹni, owo ori wa ni ẹ o fi ṣe. Ṣugbọn ngo si tun sọ siwaju pe nitori eyi ni mo ṣe sọ fun nyin ṣiwaju pe, ti yin nilati ri pe ẹ ko na owo ori wa ni inakuna, ẹ ni lati m eyiti o pataki julọ ninu ohun gbogbo ki ẹ si ṣe. Ohunkohun ti ẹ ba si dawọle, o fihan pe ẹ mọ bi o ṣe ṣe pataki si ni, ni itori eyi ni o si yẹ ki ẹ le ma tiraka lati ma pari wọn.

Ki nto ju gẹge mi silẹ mo bẹ nyin ki ẹ gba mi laye lati fi tọwọtọwọ b ẹ nyin ki ẹ ma fi ṣuru gba imọran ati ibikibi nipa ki ilu ba le toro. Ẹ maṣe sọ eto iṣelu di ohun enikan ko gbọdọ ni ẹnu si, ẹ fun dede awọn ti o yan nyin sibẹ ni iwuri, ẹ ma tẹ eti si imọran atata, ki ẹ si ma fi suru ṣe alaye fun awọn alaimọkan. o ma ndun emi pe ọpọ oṣelu ni o ro pe Faji ni iṣẹ ilu, ọpọ ni o ro pe nitori ati di oloruko ni, ti nwọn ba si wọ ile iṣelu, nwọn a gbagbe ileri wọn. Ju gbogbo rẹ lọ, ẹnyin oṣelu Ilaro, ẹ jọwọ ẹ tun ọja ṣe, ẹ tun ode gbọngan Oronna ṣe, ẹ pari awọn iṣẹ ti ilu ti bẹrẹ ni ọdun gbọrọ sehin, ki ẹ si ri wipe ile idalẹnu pọ ni ilu, ki awọn ara ilu ye da ilẹ nu si ibikibi.

Emi ni
Afọlabi Ọlabimtan

# ASIWERE ENIA NI WIPE IRU ON KO SI.

Okunrin kan wa larin ilu ti oni agbara pupọ ju ẹnikẹni lọ ni arin ilu, kosi onisẹ sise rẹ bẹna sini kosi ẹniti ole fi ẹhin rẹ lelẹ ni ijakadi, sugbọn ni ọjọkan otun gburo wipe ẹnikan wa ti onjẹ Alagbara oko, eyi mu ki ori rẹ gbona pupọ wipe iyẹn ni wipe alagbara miran tun wa lẹhin oun yi. O si pinnu li okan rẹ lati lọba alagbara oko yi ja ki on si paa kio maba si alagbara miran lẹhin on mọ

Ni owurọ kutukutu ọjọ kan oki esin rẹ molẹ odi ganri fun. on papa si dira ija dani, nigbati onlọ lọna oko na ti oju nkan ti esin rẹ yi kosi sare to nitirẹ ofi ibinu sọkalẹ lori ẹsin yi osi gbe esin na le ejika rẹ osi ngbe sare lọ bi mọto, nigbati o yọ si ahere alagbara okunrin yi ko gbe ẹlin rẹ silẹ rara lati le kọkọ fi iyen d'ẹruba alagbara oko.

Ṣugbọn nigbati ode ẹnu ọna ahere yi. iyawo alagbara oko ni o kọkọ ri sugbọn eleyini wo firi osi kọ oju kuro lara rẹ, eyi lo kọkọ ya alagbara ile lẹnu wipe obinrin yi ko tilẹ sebi ẹni wipe ẹsin ti on gbe kọrun jọ loju rara.

Nigbati on papa tun sunmọ obinrin yi dada ori wipe ekurọ lonpa lọwọ ati ojugun ni osi ti npa ekurọ na pẹlu omọlọta ti otobi bi ori enia. lẹhinna oki iya yi osi bere wipe alagbara oko ni on nbere, obinrin yi si dide owipe A! bale mi ti sunlọ. sugbọn o sọpe ki oji fun on nitoripe on nfẹ lati ba sorọ pataki ni, nigbana ni obinrin yi bọ si origun ile wọn nibiti wọn ko ọmọ odo ti wọn fi ngun iyan si ogbe meji jade, osi wipe ki okunrin yi ran on lọwọ lati ba on ji bale on yi nipa gigun ni ọmọ-odo. bayi ni awọn mejeji se ko ọm'odo ti Alagbara oko ninu ati aiya fun nkan bi ogbọn iṣẹju ki o toji, olaju o si na pọnpọn ki o to dide, nigbati o si dide o bọsi idi gorodomu nla ti wọn fi nse ọbẹ o si fi ọwọ fa ori malu kan yọ nibẹ oju si ẹnu lẹkansoso pẹlu iwo ori rẹ, o fi ehin rẹ ti o nipọn run kunna o si mi patapata lẹhinna o sunmọ origun ile rẹ o si mu ọkan ninu ọmọ'do ti wọn ki ji loju orun o bẹrẹ si fi ta ẹran ti o ha lehin danu.

Nigbati ose eyi tan on eti nrin on o si bọsi idi igi iroko ti o wa lẹhinkule rẹ ofo mọ o si fa ẹka nla kan ya tori igi iroko nla yi, o ti ibi ewe rẹ pelu ẹka bọ iho eti rẹ o si fi nse iyenye re eti rẹ na.

Nigbati alagbara ile ri gbogbo eyi idi rẹ di omi o si ti bẹrẹ si tọ si sokoto ehin losi fi rin jade k o to fi ẹsẹ fẹẹ, laiduro gbe ẹsin rẹ mọ, loba sa wale.

Nigbati awọn ara ile bere ohun ti o ba bọ ati wipe ibo ni ẹsin ti o se lọsọ dada ni gbe wa, odahun wipe baba jona ẹmbere irungbọn kiba ni ina kọkọ mulọ, eyi mumi ranti owe awọn baba wa ti o wi bayi pe Eniti ko ba de oko baba ẹlomiran, ni wipe kosi oko baba ẹniti oto ti baba on

Olotu, modupẹ aye ti ẹ gbami o. Odidẹrẹ ki ku si oko iwajẹ, ayunbọ ni ọwọ oyun ẹnu, ẹ o ko ere oko dele o' Ọko ọba kosi ni sayin lẹsẹ.

Njẹ emi ọmọ Aribọdu nrele o, ọmọ Oloramọnle oju gbele eju yan igba oko titi gbọnti mọ lulu Ọra.

Lati Ọwọ
J. A. ADENIRAN
Ọmọ-Olora
ỌTUN-ORO

## Jimoh Komojade

Takwa Ghana

Ni ọjọ atalata ti ise ọjọ keji osu ti o kọja yi ni Ọlọrun fi ọmọkunrin kan ta Jimọh ati iyawo rẹ Rabiatu Adunọla lọrẹ, wọn sẹ ikomọ na ni ọna ti Musulumi. Alufa Rufai ni o se ikọmọjade na, won sọ ọmọ na ni Abudu Ramanu. Inawo ọjọ na buaya, o le gongo, ajẹti ni awọn alabaseyẹ jẹun lọjọ na, ese ni ọti nrọjo, amutakiti ni.

Diẹ ti aye wa fun lati darukọ ninu awọn alabasẹyọ ọjọ na ni S. Adigun, S. Alabi, E. Adara, Lasisi Tailor, A. Atanda, A. Akanji, Salami ti ko kọla. Edumare yio wo ọmọ na, yio si fi ire kari o. Aṣẹ

# FADAYIRO LO KO ILOSIWAJU IGBIMO NI ILU OYINBO



Aworan ti ẹnwo loke yi ni ti Ọgbẹni alabojuto ọrọ awọn ẹgbẹ Ijọba ile igbimọ ti ila-Orun ni ilu Naijiria, Oloye E. A. A. Fadayiro wa ni ilu oyinbo nisisiyi nibi ti o nkọ ilọsiwaju ile ilana igbimọ ọba, oun ni a ri ni apa ọtun ninu aworan oke, ti Major Lockhart ẹniti o jẹ akọwe ti igbimọ apapọ, awọn enia nki nigbati o de si ile igbimọ (House of Commons)

Fun oṣu meji ti o ma fi wa ni ilu oyinbo, Oloye Fadayiro yio wa ni ibiṣẹ ti olori ijọba ti o nbojuto iṣẹ dede esi awọn ẹgbẹ ilu ni Westminster.

## EJILAMI KOMO JADE

TARKWA GHANA

Ni ọjọ alaruba ti iṣe ọjọ kerindinlogun oṣu ti o kọja yi ni Ọlọrun fi ọmọbirin kan ta Bello Ejilami pẹlu iyawo rẹ Jarawu Aṣabi lọrẹ, wọnṣe ikomọ ọmọ na ni ọjọ kẹjọ ti iṣe ọjọ keji oṣu, wọn si sọ ọmọ na ni Mọdinatu. Baba ọmọ na fi jijẹ ati mimu tẹ awọn Alabaṣẹye ọjọ na lọrun.

Awọn ti aye wa fun wa lati darukọ sinu iwe yi ni awọn Ọgbẹni Mọṣudi, Karimu, Tijani, awọn ọrẹ baba ọmọ lati Dombim. Ezekiel Adara, Sule. Asani ati awọn enia pataki-pataki ti ko si aye lati darukọ wọn sinu iwe yi. Ọgbẹni S. Adigun Tarkwa dabira lọjọ na. Ki Oluwa da ọmọ na si. ki o si pin ire na kari.

## Igbeyawo Akin. Adekunle Ogunjobi larinrin

Irohin ko to afojuba nigbati Mr. Akin. Ogunjọbi ngbe Miss. Victoria Idowu Kẹhinde ni iyawo ni Ṣọọṣi Eleto ni Ode Ijẹbu Rẹmọ. Mr. Dapọ Kẹhinde lo fa iyawo na lọwọ titi lọ de Ṣọọṣi, ki Mr. Joseph ọnadele ti iṣe aṣoju ọkọ iyawo to gba lọwọ rẹ lati mu lọ si iwaju pẹpẹ fun idapọ mimọ iyawo na, aṣọ oke ati buba olowo giga ni iyawo na lo, o si ja itanna lọwọ, ọkọ iyawo na si lo iru aṣọ oke ti iyawo na gẹgẹ. Awọn ti o wa kakiri ilu ko ṣe fẹnu sọ, Taiwo Ojurilo ya aworan ọjọ na. Ki Oluwa k i o fi ọmọ rere ṣekẹ yin. Aṣẹ

